The Chief Secretary to Government, Lagos, Nigeria.

P. A. Obasa
Editor & Proprietor "Yoruba News" Ogunpa Rd Ibadan


# The Yoruba News

**FOR GOD, THE KING AND THE PEOPLE.**

VOL. II. No. 22 IBADAN TUESDAY, JUNE. 9, Price 3d. Weekly.


19 JUN 192[illegible] LAGOS


## S. AGBAJE & CO.,

***General Merchants***

HEAD OFFICES:
GBAGI & AYẸYẸ MARKET,
Ibadan, Nigeria.

Suppliers of:
**Palm Kernels, Palm Oil, Cocoa, Maize, Rubber, Ivory &c, &c**
also
**MOTOR TRANSPORT SERVICE**
**Throughout the Western Provinces of Nigeria**

## S. ABINUSAWA,

*Motor Mechanic,*
*Ogunpa Junction, Amunigun Mart, Ibadan.*

EXPERT REPAIRER
OF
Motor Cars and Lorries

Bring all your Sick Motors for curing.

CHARGES MODERATE

## L. L. RICKETTS,

***AGRICULTURIST.***
YEMETU STREET,
P. O. Box. 136. IBADAN.

Expert advice on the Agricultural Resources, Yoruba Land will be given to Amateur Planters on Application:—

Instructions with regards to Soil, Planting, Planting Seasons and the general routine of cultivation.

Selected Plants of Gbanja Kola are supplied on reasonable terms and various useful plants including fruit trees etc., etc., etc.

Also Instructions on the preparation, handling and storage of produce. An interview will prove interesting.

Correspondence will be carefully attended to

## White's Golden Female Tonic

Splendid Remedy for Female diseases such as - Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhoea *Whites* Cramps Ovarian, Neuralgia. Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc etc.

Made and sold only by Victor White Esq
41, Offin Road Lagos.

*N.B.* Not obtainable elsewere.

## Gbogbonise fun Obinrin

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Oyun, ti o ba fẹ baje, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

Boxing & Postage 2/-6 extra.

## White's Golden Male Tonic

"DOUBLE-STRENGTH"

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic "Double-Strength" is alculated to give full vigour to the man, and to remove al disease which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by Victor White Esq
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road Lagos.*

N.B. Not obtainable elsewhere.

## Aremo fun Okunrin

Nigati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

N. B.-- O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu --iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottles

Boxing & Postage 2/6 extra.

PRINTING!

PRINTING!!

**PRINTING!!!**

All Grades of

**ARTISTIC,**

**COMMERCIAL**

AND

*GENERAL JOB-PRINTING*

*ALSO*

*BOOK-BINDING,*

Neatly executed at Moderate Prices

AT

## THE ILARE PRESS

Ajaba Square,

Ogunpa Road,

P. O. Box 60. IBADAN.

# Isaac F. Karunwi,

*Mechanical Engineer,*

# *Brookley Garage.*

*ONIREKE ROAD, IBADAN.*

Care P. O. Box 86,

Undertakes repairs to Motors.

Portable Engines & Machineries.

Typewriters. & Gramophone repairs a speciality.

EST. JAN. 1 1918

## OWUYẸ.

ORỌ BURUKU! ẸSUN MB' EDI?

Ọkunrin kan ara Ile Olukosi fi abẹ fa ara rẹ ni Irin-isẹ-ibimọ tabi "Itan kẹta," o si pọn ọn si inu ewe; o pe ọmọkunrin kan, o ni ki o "gbà a fifun wọn, ohun ti nwọn ni ki oun mu wa ni yi." Nigbati ọmọkunrin yi gba a ti o tu u wò, igbe lo fi ta.

Nwọn ru ọkunrin nã wa s' ile lati oko wọn ti o gbe se inkan yi.

Ki Ọlọrun gba ni lọwọ Bilisi ati Alusi gbogbo.

Lati ijejidinlogun ti Ṣitu, Bãlẹ Ibadan ti lọ si Ọyọ, onirũru irohin buburu, ọkan-ko-jọkan, ni a nri gbọ lati ọhun wa; Bãlẹ ko si ti i pada de di isisiyi.

Afara Gẹgẹlọse ti Iɉoba sẹsẹ tunse dara pupọ nitori o gbaye fun mọto meta lati rekọja pọ laisi ewu.

Awọn Ijoye Ibadan ti bẹrẹsi lọ ṣan oko oju Odo Ogunpa sẹhin nitori ki omi le mã ri aye ṣan kọja lọ.

## ỌFA.

Messrs. C. A. Kasumu and E. A Simplice both of Lagos came up on a very urgent business on the 2nd inst, and returned next day.

Mr. Daniel Adelusi Ojo of Posts and Telegraphs Department arrived from Jos: on 5/6/25 he retired on pension after 22½ years service; we understand his retirement was due to ill-health; we wish him a long earned pension.

Mr. Joseph K. Majarọ, clerk in the Locomotive Department, who went on three weeks leave to Abẹokuta returned here on Tuesday morning the 5th insant.

Ẹ ku abọ o.

## Orin ni Iranti

CHARLES LADIPỌ ỌDẸBIYI

O SE! ARAKUNRIN MI!!

1. Enia Ọlọrun E ku 'rọju,
Enia Ọlọrun Iku d' oro,
T' o gba Charlie Fau Lọwọ wa,
Iku doro Enia Ọlọrun.

Chorus:—Odigbose, Odigbose,
Orakunrin, Odigbose
Odigbose, Odigbose,
Ladipọ wa Odigbose.

2. Ijọ 'Badan, Ẹ ku ọfọ,
Danmọle wa, Ko wi tẹlẹ:
Pe bayi ni, Lilọ yio ya;
Ao pade ni Paradise.

3. Kil' adun na, To wa l' aiye
Nigba t' iku Nm' ẹni 're lọ?
Agbọ-ju-gba-nu 'hin Kikoro,
Amereya 'Gbagbọ wa lọ.

4. Baba-Agba, Ibijọpe,
Aderẹmi, Iku d' oro;
Ẹ f' ọran m' Ọlọrun l' ọkan,
Jesu l' o gba, Ladipọ lọ.

5. Konigbagbe, Ni Iku rẹ,
Ẹkundebẹ, Ni Iku rẹ;
Afẹku rẹ Se wa laisan
Odigbere! Ọdawurọ.

6. Edumare, Onibu-Ọrẹ,
Ma wo 'wa wa, Ṣẹ 'darijin
Ṣa ka wa m' Ajogun 'gbala,
Ka ba ọ jọba Paradise.

Odigbose, Odigbose,
Arakunrin, Odigbose
Odigbose, Odigbose
Ladipọ wa, Odigbose.

ANSWERS TO PUZZLES.

The answers to the last Puzzles are:—

(1) 1, 2 and 3.
(2) ten
(3) 1 and 0.

## ABẸOKUTA.

Ọgbẹni A. S. Latunde akọwe "Book-shop" ni Abẹokuta ti o lọ ṣe Igbeyawo ni Eko ṣe ijade Iyawo rẹ ni Ṣọṣi Sonde 3/5/25; a si gbọ ẹwẹ pe Iyawo na gbamuṣe—ọmọ pupa bi Orombo, a ki ọkọ Iyawo ati Ẹbi rẹ ku inawo..

O si dun wa pe awọn Ọgbẹni Luwaji Lipede ati O. K. Adetutu ko si ni ile, wọn i ba fọgi nibi Iyawo na. Ṣugbọn a dupẹ lọwọ Ọgbẹni I. B. Ṣofoluwẹ ẹniti o sunmọ ọkọ Iyawo girigiri ti ko jẹ ki a mọ pe awọn meji yi ko si nile.

O gbà pupọ fun awọn Ledi ati Jẹnti ti nwọn lọ si ibi Ipe yi.

Iyawo yio mã bi. yio si ma rẹ; Aṣẹ.

---

Anu ṣe ni lati gbọ Iku Ọgbẹni Daniel Akinbọ Ẹgbọn Iya Oye, ẹniti o ku ni Fraide ọsẹ tọhun 22/5/25 ti a si sin oku rẹ ni ọjọ Satide 23/5/25; nwọn ṣe ijade rẹ ni ọjọ ọsẹ-ijẹwa ni Ṣọsi Ake. [illegible] Ogbeni [illegible] ẹniti o sin oku na, ati awọn ọmọ Ẹgbẹ R. O. Plumptre (Ẹgbẹ Irẹpọ) Ẹ ku aṣẹbinde.

---

Eni-ọwọ J. J. Ramsome-Kuti ati Ọgbẹni R. A. Plumptre wọ ọkọ ni ọjọ Mọnde 26/5/52 lati lọ sin oku kan ni Ọpẹji, anu ṣe wa pe ojo rọ pupọ ni ọjọ yi. Ṣugbọn wọn ko bikita lati de ibi isinku na ninu ojo. Ẹ ku iṣẹ emi.

---

A gbọ pe owo bi (£58 0. 0.) poun mirindinlọgọta lo bọ ni apo awọn ọmọkunrin ti o lu enia ni ibi Ferewa si apo Ijẹba. Ara Odo, o dọwọ nyin o.

B' o ti wu ki a ṣe àpá ko ni jọ ara o.

---

A ki Alaiye, Ọba Alake nipa Inawo pupọ ti o ṣe ni titun ode gbangba rẹ ṣe ti gbogbo rẹ si tẹju lọ rẹfẹlẹ. Ki Olodumare ran a lọwọ; Kabiyesi o!

---

Awọn ọmọ Ile-ẹkọ ni Abẹokuta ko lọ si ibi Ipade wọn ni ọdunni; eyini ni "Race Course" nitori arun ti mbẹ lode yi, nitorina ni olukuluku ọmọ Ile-iwe ṣe ṣe Ire ni Ile-ẹkọ wọn gbogbo.

---

## ỌFA.

Ọgbẹni J. A. Adebiyi, Ọga akọwe ni *Loco* Ọfisi, dabira ni ọjọ yi niwaju ile rẹ ni Sabongeri, ni dẽde agogo marun irọlẹ. lẹhin ti ojo da. Ọgbẹni yi pe awọn ọmọde jọ fun onirura Ireje: gẹgẹbi ere sisa, kiko sinu apo ati orisi idaraya mĩ ti a ko le daruko tan.

Ẹnikẹni ko mọ igbati Ọgbẹni nã ngbero inkan alarinrin yi; inkan nã si gba tobẹ ti a ko le mọ ohun ti a le fi i we, Ni ọjọ keji ere, June 4, Ọgbẹni Adebiyi pin ẹbun fun awọn ọmọde gẹgẹbi ipo onikaluku.

Adura wa ni pe ki Oluwa busi apo Ọgbẹni yi.

---

## IJẸBU-ODE.

Omidan Vic Abiọla Onọbanjọ ko awọn ọrẹ rẹ diẹ lẹnu jọ ni agogo mẹwa awurọ Sọnde ni iranti ọjọ ibi rẹ pe ọun di ẹni ọdun mọkanlelogun. Bi o ba ngbọ kẹrẹ kẹrẹ ẹsẹ ẹsẹ bata awọn ọmọ eriwo ni o ngbọ yẹn o bayibayi ni ki a mã ri o.

### Empire Day.

Ajọdun ti Empire Day bẹrẹ nibin ni Satide ọjọ kẹtalelogun oṣu May toripe ọjọ nã bọ si ọjọ Sọnde. Torina awọn ọmọ ile-ẹkọ ṣe diẹ ninu ire wọn ni ọjọ nã, nwọn si ki Aṣia ni ọjọ Mọnde.

Ojo ko tun jẹ ki nwọn pari iṣẹ na ni Mọnde, nwọn si wa pari iyoku ni Tuside May 26.

---

Orin yi ni a tun le kọ fun awọn ara wa ni akoko yi. nigbati o jẹ pe, pãnu gari ti a ti nra ni kọbọ kan abọ di tọrọ. Ọlọrun Ọba Kokoibere n à gba ni o.

### Ajayi a gbadun rẹ o.

Labẹ Ọgagun Ọgbẹni E. O. Ajayi, awọn "Boy Scouts" ti Ijẹbu Ode ṣe kisa ni ọjọ Monday ọsẹ yi, wo mi ẹnikeji, bi o bari bi awọn ọmọ na ti nṣe, ō gbadura pe ki Ọlọrun fun ọ ni ọmọ ki o lọ ṣe "Scout." Ti Ọgbẹni wa na ẹlẹrin ẹyẹ nyan tikẹ niwaju wọn ! Ajayi, o kare ! Ọmọ l' ō fi le lọwọ.

Odudemiran kare o ! Ọmọ Ogbolu. Ọrọ ko di gasikiya bi ? ọmọkọnrin yi jafafa pẹlu iṣẹ rẹ ( *Smart* ) bi o bari i bi o ti nyan niwaju awọn ọmọ *School* rẹ ti Ijọ Olugbala (St Saviour's), aṣan yiyan nā to lọtọ. Bi o ba ri jagun bi o ti duro wāmu bi egbin.

### IJỌ KAN L O SE EYI BI ?

Ẹniti o ba ri Iboji Ọgbẹni C. L. Ọdẹbiyi ologbe ni Idi Ikan, agbayanu ni i "Ọrun l' ọpọlọ ti mu awọ ifan w' aiye agiliti a b' ara yiyi" Ọrun ni arakunrin na ti mu ori okiki w' aiye; Ajikẹdidun Ijọ Onitẹbọmi ẹ ṣe o ! Oluwa yiō bu sinu apo nyin, a ko le ṣai sọ nipati iboji ọrẹ wa na ; nitoripe ẹniti o ba fi oju kan a ni yio mọ ihin re irō ; a ko le mā sọ ọ lọ titi bi nwọn ti ṣe e ni iṣẹ okiki to : nitoripe ẹniti o sun nibẹ na olokiki ni i. Ṣugbọn ọpẹ yẹ fun Revd T. O. Dawodu Alufa wọn ati fun awọn bi Ọgbẹni E. N. Phillips Deacon wọn, T. A. Ojo D. A. Ọbasa, L. L. Richetts, D. Tolu A. Ojelabi ati awọn bi J. Larinde, E. S. Debari pẹlu awọn miran ti a ko le ma sọ orukọ wọn. Eriki na jẹ ẹnikan ti a ko le gbagbe horọ sibẹsibẹ Oluwa yio tu nyin ninu o.

Ki a ranni ni ise, ko to bi ki a mọ ọ je a si yin Birikila (bricklayer) Titus Amọdu fun iṣẹ agbayanu ti o ṣe si Iboji ọrẹ wa na. Ẹniti o ṣe ẹhinde oku yio ri ẹni ṣe lọ ẹ fun oun na o

Okunnọla

### IDANA,

ỌMỌ FALỌLA MO NGBADUN RẸ !

Ni Tọsite ijọ kerindinlogun osu April ni Ọgbẹni J. A. Falọla ṣe Idana iyawo rẹ, Omidan Adunọla Ọmọnikẹ.

Awọn ọbinrin ti nwọn lọ sibẹ to ọgbọn, lai ka awọn ọmọge. Iyafin Bolumọle ati Iyafin Christopha ni nwọn ṣe aṣiwaju ēto nā, a si gbe awọn Igba nā lọ tilùtilù, Nigbati awọn ti nwọn gbe Igba lọ pada de, ti nwọn si jiṣẹ tan ki o wa ri bi awo Ẹyin Tanpẹpẹ (Rice) ti nkọlu ara wọn kẹ-kẹ̀-kẹ ; ati ohun mimu bẹ̀ pẹlu, ọmọ Falọla mo "nsala" ẹ o ! Diẹ ni a le rohin ti ọjọ Idana yi mọ.

Ni Sọnde ti o tẹle ti Ọgbẹni Falọla lọ dupẹ ni kungu fọ. Mọto Ayọkẹlẹ L852 eyiti Onwà rẹ njẹ Akande. (onwa nā sa nwa bótò) ni ọkọ Iyawo gba, ki o ri bi awọn ọmọge ati ọdọmọkunrin ti pesẹ lọdọ ọkọ Iyawo. Mọto yi wa npōyi bi arirā lati Amunigun lọ si Popo Labiran ni ile Iyawo.

Ọhun dùn. Tabili ti nwọn pese silẹ bi o ti gùn lọ rakabo to ko si tun gba gbogbo wa tan, nwọn ni lati tun pese omiran si.

Bi a ti njoko, bẹni awo onjẹ nde l' ọtun ati l' osi ; bẹ si ni ohun mimu pẹlu. Emi ni tirẹ, iyoku iregbe, nigbati awọn janmọọ yio fi fi ohun silẹ, igi da "Oku adiẹ ko mọ ẹniti o ntu oun mọ."

Nigbati a tuka lori tabili tan, ọkọ̀ Ayọkẹle yi tun bẹrẹ wayi o. A ṣe diẹ ni ti ile Iyawo ? Nigbati a tun pada de ile Ọkọ Iyawo tan, onjẹ tun npe onjẹ ran nṣẹ, bẹ si tun ni ohun mimu pẹlu ; melo ni okanjua yio la ninu apo iyọ ? Ọpọlọpọ lo fi ọwọ ṣe ẹṣẹ dele.

Ki Oluwa mu Iyawo de ile ni alafia

Ọrẹ Ọkọ

### NOTICE.

We take this opportunity to remind our subscribers whose subscriptions have become due to send them in as early as possible.

## THE YORUBA NEWS.

*Editor & Proprietor:—*

D. A. OBASA,

Office-AJABA SQUARE, OGUNPA ROAD
P. O. OX 60, IBADAN.

*Subscriptions payable in Advance*

Ibadan Is, per annum. 14s Post Free.
Cheques and Orders should be crossed and forwarded to the Editor.
Advertising rates &c. on application

## The King's Birthday 1925.

KING'S Birthday was celebrated last Wednesday the 3rd instant with the Parade of the Troops on the Race Course at 8 o'clock a.m. The function was attended by the leading Government Officials, Mercantile Agents, Ministers of the religious bodies; Schoolmasters and the intelligent members of the community.

In the absence of the Balẹ of Ibadan who is at Oyọ still this writing, the Chiefs headed by Oyewọle, the Balogun of Ibadan with Amida the Ọtun Balẹ attended with their retinues.

After the inspection of the troops by our gallant District Officer, Major Williams-Thomas, D.S.O., L.L.M, three loud cheers were given in honour of His Most Gracious Majesty the King-Emperor.

We congratulate the O.C. Colonel Burney and staff upon the smart appearance of the men.

GOD SAVE THE KING

### EMPIRE DAY Ọwọ, 1925.

Empire Day falling on Sunday this year, a service was appropriately held for the children of the Empire in St. Andrew's Church (C.M.S.) at 3. p.m. of that day, which was attended by the children with their teachers from the Government and St. Paul's (C.M.S.) Schools.

Revd. T. Aderinola the Pastor, an earnest preacher, was the Conductor of the service. He took his text from Prov.1 10 "My son, if sinners entice thee, consent thou not." He pointed out how Solomon the wisest of all men was the writer of this book of Proverbs, and yet still, in spite of all his wisdom, he was led astray from the path of righteousness, and God took away his Kingdom from him and gave it to a servant. From this he showed how "The fear of the Lord is the beginning of wisdom."

The pastor next gave an interesting life history of Bishop Samuel Adjai Crowther in a very concise way, pionting out how his early childhood prophesied his future career. His bravery in rescuing his father's goods when their house took fire made people say that, he would be a great worshipper of gods, and that he would restore them into their land in a greater number. The result of the consultation of Adjai's parents with an Ifa Priest was that he was to serve the great sky God. This frightened his parents, because the only worshipers of the sky God of those days were the Fulanis and these apparently were the enemies of the Yorubas—the people of Adjai's native land.

Unfortunately, war came and Adjai was captured and, was sold from hand to hand until he was sold into the hands of the Europeans who eventually gave him his liberty and education.

It was Bishop Adjai to whom the abolition of slavery by Queen Victoria was due because he stood in the presence of the Queen and told her how he had come to be in England. The Queen having pity over him, and being sympathetic with the Negroes as a race bade Adjai go, assuring him the consequent abolition of the trade in slaves.

Peace came to the Negroes, a blessing

ASAN SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ

Ibadan Ilu Ẹhin Odi.

| | | |
|---|---|---|
| dun kan | 12/ | 14/ |
| Osu mẹfa | 6/ | 7/ |

Ẹ fi owo pẹlu *Letter* ranṣẹ si *Editor*

through the influence of the Great, Good Queen and which has since and forever made her name imperishable. Another type of this character was found in Esther, a queen of King Ahaswurus, who endangered her life to emancipate her people, when they were plotted against by their enemy.

Adjai rose to be a Tutor, a Priest and finally a Bishop ; and what was at first thought a misfortune was a great fortune indeed. Children who suffer at school now-a-days need not think themselves the most unfortunate creatures that lived; because crops never come before toil, but after. The present children of Ọwọ are responsible to build it up with frames of pure Christianity and civilisation in future.

The service was brought to a close by the Pastor after pronouncing the Benediction. The amount of silence maintained by the children helped to make the service impressive and solemn.

It had been proposed to have Inter-School Sports on Monday the 25th May for which the District Officer had offered £3. According to the programme, the Sports were to commence as early as 7 o'clock a m. but as luck would have it, it began to rain at a few minutes past 7 and though the rain was light, it did not cease till about 11 o'clock.

The Sports began at 12.30 noon with a Football Match between the Government and St. Paul's (C.M.S.) Schools and after 40 minutes each side, the C.M.S. won by 2 goals against nil.

With the exception of the period occupied by the Football match, the Rev. C.W. F. Jebb, the *Superintendent* was the M.C. for the rest of the time.

The display was well attended among the onlookers were a European, Mr Forest of the P.W.D., Chief Sasere, the Vice-President and the elite of the town. The dead of night crept over the Sports and so it was impossible to decide the prizes that day. That the School Children and their Teachers were feasted to their full need not be emphasised here.

The prizes were awarded on Tuesday morning, May 26th by Rev. Jebb in the Government School. The prizes were all in money and were gratefully accepted by children.

God be praised ; there was no accident of any moment throughout, excepting that of a boy who received a kick of the foot-ball on his nose and caused blood to trickle out of his nostrils ; this was about 5 minutes after the match commenced. The 2nd was that of the Head-master of St. Paul's School —a boy of the opposite side by accident gave him a knock of his teeth on the head and blood came out in jets. This was about 5 minutes before the end of the match. The Head-master, who is also the Scout-master suggested the First Aid remedies and at once began to play on "smiling" as a scout only knows how !

The Celebration of the Empire Day in Ọwọ this year has been the first of its kind. The President and VicePresident respectively offered 5/- enthusiatically regretting that they were not notified in time or they would have done better.

Much praise is due the teachers of the Shools in Ọwọ for making the celebration of the Empire Day a success.

---

The Programme of events for this occasion, News of Ọwọ, Ijebu Ode &c, will appear later.

Ed. Y. N.

## ILEṢA.

18. 5. 25.

Eni-ọwọ S. A. Oluyẹmi lọ si Abẹokuta fun ọsẹ kan lati lọ simi diẹ. A si ni ireti pe yio pada de ni ẹhin ọjọ ọsẹ ti mbọ yi.

29.5.25

Awọn ọmọ Ile-ẹkọ ti Wesley Ọtapẹtẹ gba isimi loni yio si di ibẹrẹ oṣu Julai ki wọn to tun bẹrẹ iṣẹ wọn.

31 5.25.

Ni oni ni nwọn pin ẹbun fun awọn ọmọ ti nwọn ṣe dada ninu Idanwo ti awọn ọmọ Ile-ẹkọ Ọtapẹtẹ ṣe. Ẹbun nā si pọ pupọ. Ẹni-ọwọ R. S. Oyebọde ni o se alaga ajọ nā a si pe Katikist ti Oṣogbo lati wa ba awọn ọmọde ṣọrọ.

1.6.25.

Awọn ọmọ Ile ẹkọ yi tun sa ire ije (Sports) lọni awọn ọmọ si ṣe ere ti o wu enia lori pupọ.

Nwọn ni ti enia ba ṣe inkan rere, ti o si tẹ ni lọrun nṣe ni ā yin ẹniti o ṣe ohun na. O dabi ẹnipe Alabojuto Ijọ—Ẹni-ọwọ John Stewart mọ riri iṣẹ ti awọn oluko Ile-ẹkọ Ọtapẹtẹ nṣe ja bi awọn obi ọmọ lati Ijọ ti mọ 21. Idi rẹ nipe ni esi (1924) o fun Ọga Ile-ẹkọ yi ni owo pe, oun jẹ dọdọ iṣẹ ti Ile-ẹkọ ti Oṣu ṣe, l'ọdunni, o tun fun awọn t'ẹgbọn t'aburo ti nṣiṣẹ ni Ile-ẹkọ yi ni owo pe oun gbadun iṣẹ wọn pupọ. Bẹbẹ ni ki a mā ri o. Ẹyin Tiṣa, ẹ tubọ mura s' iṣẹ o.

## ẸGBẸ IFẸ. TI IJỌ ST. MICHAEL. KADUNA.

Edito, Iwe Irohin Yoruba,

ALAGBA,

Jọ bun mi laye kinkin ninu iwe Irohin rẹ; oun ti mo fẹ sọ ni pe, gẹgẹbi owe awọn baba wa ti sọ pe "Ẹni yin ni, k'ẹni tun se mi si i"; toto o, apẹrẹ rere kan tun ja le lati ọdọ awọn Ẹgbẹ yi ni Tọside ti ọjọ keji oṣu yi nigbati Bature Maidubogeri (Ebo wole-wole-Sanitary Inspector) pe Joshua Ọkẹ Babasalẹ Ẹgbẹ na lẹjọ:—ko ma ja a lo le o, bẹni ko gba a lobirin, ṣugbọn ki a sa ma gbadura pe k' Ọlọrun gba ni lọwọ akowaba, Amin.

Obirin ọkan ninu awọn ti ngbe agbo ile rẹ (Joshua Ọkẹ) l' o ṣe amodi ti ọkọ obirin na si nṣajo pe boya a tete san; ọ tan, ni nwọn fi imu finlẹ titi ebo na fi gbọ. ti o si lọ pe Joshua l' ejọ pe ko tete wa ripotu pe alamodi mbẹ ni Agbo-ile oun.

Lojukanna ti awọn Ẹgbẹ gbọ ni wọn pa 'nu pọ pe ki nwọn fun Babasalẹ ni ogun ọkẹ owo (£5) nitori aibamọ; iwọn ọkẹ mejila (£3) ti o wa ni arọwọto Ẹgbẹ, Daniel Alu fi ọkẹ owo meji kun u lọwọ ara rẹ ni wọn ba ko o fun Babasalẹ. Ni Mọnde ijẹrin (14.5.25.) ni Kantonmẹnti da ẹjọ nà "Agbija Ọba ki sa jẹbi."

O ni ki Babasalẹ san ẹgba-mẹdogun (7s 6d) si apo ọba; o san owo na lapo ara rẹ o si da owo Ẹgbẹpada pẹlu ọpẹ. A ki Ẹnyin Ẹgbẹ Ifẹ, ki Ọlọrun ma jẹ ki Ifẹ nyin ma tutu o—Babasalẹ k' Ọlọrun fi ọran mọ bẹ o

Lakunmọlẹ.

Kaduna. 15.5.25.

## IṢẸ TI A TI ṢE NI EJIGBO.

Inu wa dun lati jihin pe, Iwerohin yi se awọn ara Ejigbo l' ōrẹ pipọ nipa sisọ otitọ fun wọn.

Ekinni ninu ohun ti o ti ṣe ni ilu yi ni pe: A dupẹ pe Aẹjẹ ti fi opin si Asa a-nfi-oku oloye silẹ laisin titi-yio fi rà danu tan, ti ōrun rẹ yio si gba gbogbo ilu kan.

Ekeji ni pe awọn ara Ejigbo bẹrẹsi i fi owo wọn ra Mọto fun anfani owo ilu wọn. A dupẹ fun iyipada yi. Ohun kan ti o ku fun wọn ni pe: ki awọn ara Ejigbo mā ra iwe Irohin yi (Yoruba News) ati awọn miran ti a ntẹ ni Ile Eko, ki nwọn le tubọ mā ri oye si i. Imọlẹ de, Okunkun ti fo lọ!

## MINNA NEWS.

FROM A CORRESPONDENT.

Mrs. Johnson wife of Mr. Johnson gave birth to a male child on the 19th instant. The child was "brought outside" on the 26th instant as is the custom of the Sierra-Leonians to keep a babe indoors for seven days before showing it out. This is a prognostication of good omen for the babe. We regret to announce that unfortunately this child died on the evening of the 27th instant. This is the second loss that Mr. and Mrs. Johnson have suffered; the first was about the year 1923. Our sincerest sympathy goes to the bereaved family.

The Inspector General of Police, Northern Provinces returned to Kaduna on the 22nd instant.

The observance of the Empire Day was made on Monday the 25th instant. At 9 a. m. all the School children with the exception of those of the Faith Tabernacle School (Faith Tabernacle courtesy) were in attendance at the African Tennis Club's play ground, just in front of the Sudan Interior Mission Church and a few yards to the market place. The School Children totalling about 80, composed of Roman Catholics 36 and C.M.S. about 44. The Acting Station Magistrate Captain R. D. Ross and the A.D.O. I/c Provincial Office, Mr, L. H. Goble, were the only Europeans present.

The Acting Station Magistrate delivered the Empire Day Message.

Two potographs were taken but owing to shortage of photographic materials, copies will not be available for some time. Finally Mr Heald of the Dist. Engineer's Office distributed sweets and biscuits among the School children.

On the 10th instant the Faith Tabernacle Church members invited the Sudan Interior Missionary Church members to their prayer meetings. Two of the European Missionaries attended. The S.I.M. returned the invitation the next day. The Faith Tabernacle members accepted and promised to attend the S.I.M. Special Service on the 21st instant but they failed. The only excuse they may have. no doubt, for this Faith Tabernacle Courtesy, will be the little rain which fell that night. The other denominations though were not invited as the Faith Tabernacles attended, many of them throughout the week, 18th to 22nd inst.

On the afternoon of the 25th instant the European Minna Uphill Tennis Club and the African Tennis Club had a Tennis Tournament. The Europeans won the first three rounds. The fourth, the final, which was to settle everything was won by the Africans. The European Tennis Club has returned the challenge for a tournament on the 3rd. proximo.

It is the practice of the people here to plant corn, gero, guinea corn, pepper, okro and other vegetables in or round their compounds or a few yards from their compounds The breeding of mosquitoes is thereby encouraged. The Medical Officer has given instructions against this practice. The Acting Station Magistrate caused the Medical Officer's instructions to be the widely known on the 30th instant. Penalty £25.

The planting of vegetables such as okro etc. Sweet potatoes are allowed in compounds and surroundings

31-3 25 Minna

## H. N. THOMPSON ESQ. C.M.G.

One of our popular Government officials is H. N. Thompson, Esqr. C.M.G., the Director of Forests

Mr. Thompson is affectionately called 'Baba" by the African members of his staff and all who have dealings with him, through the kindhearted way in which he treats everybody irrespective of colour or creed. He is the right type of the pure bred English gentleman presently needed in every part of the Great Empire and especially in Nigeria. Wishing Mr. Thompson continued success in the King's service.

E ku aho!

# THE NIGERIA LABOUR CORPORATION

## EGBẸ AGBAJỌ AWỌN OSIṢẸ

Ẹgbẹ yi ti daraba, o diji, o ti dohun ọkunlẹbọ. Osiṣẹ ti ko i ti wọ, ko mo odo ti oun ndọra si. Ọmọ Ẹgbẹ yi ti le ni (500) ẹdẹgbẹta. A ko kọ enikọn, iba ṣe akọwe, tabi lebira. Ṣile kan 1/- li fi nwọ, sile mẹwa (10/-) ni owo dida ọdọdun, asansilẹ ni o, a si le da isan lẹmeji tabi jubẹlọ.

AWỌN EGBẸ YI NI A TI DASILẸ LABẸ AKOSO YI:—

| | |
|---|---|
| **The Native Nurses Union** | (Ẹgbẹ olutọju Alarun |
| **African Steamer Association** | (Ẹgbẹ Oniṣẹ ọkọ oju omi) |
| **The Post & Linesmen Union** | (Ẹgbẹ akowekiri ati Oniwaya) |
| **The African Pensioners Union** | (Ẹgbẹ Oniṣẹ Ọba to ti simi) |
| **The African Police Defence Club** | (Ẹgbẹ akọya fun Olọpa) |
| **The Motor Drivers Association** | (Ẹgbẹ Awamọto) |
| **The Engine-Drivers Union** | (Ẹgbẹ Awakọ Ilẹ) |
| **The Sanitary Inspectors & Vaccinators Union** | (Ẹgbẹ AWole-wole ati Bupabupa) |
| **The Carpenters & Joiners Union** | (Ẹgbẹ awọn Kafinta) |
| **The Painters Association** | (Ẹgbẹ akun-ọda) |
| **The Bricklayers Union** | (Ẹgbẹ mọlemọlẹ) |
| **The Printers & Compositors Union** | (Ẹgbẹ awọn Atẹwe) |
| **The Farm Labourers Union** | (Ẹgbẹ awọn Alagbaro) |
| **The Common Carriers Union** | (Ẹgbẹ Alaru Ita) |
| **The Casual Labourers Union** | (Ẹgbẹ Alagbaṣe) |

Ewo ni tirẹ, enikeji? O ba wa nile, o ba wa nidalẹ, sa fi orukọ rẹ, iṣẹ ti o nṣe, ẹniti o nsin, ibi ti o ngbe ati owo Ẹgbẹ ranṣẹ si akọwe

The Secretary,
Nigeria Labour Corporation
Iron House 4, Tinubu Street
Box 251, Lagos, Nigeria.

A ni Office ni Ebute Mẹta, ni Denton Street, l' Ẹhin Ọgba Loco Railway.

GBOGBO OSIṢẸ, Ẹ WA!

# FOR SALE.

INDIANA LORRY

## L 1107

**Quite New**

Only Three Months in use

Apply Editor

---

# TO LET

---

# HUDSON COLE,

*Builder and Contractor.*

***Undertakes & executes all kind of BUILDINGS & OTHER CONTRACTS in any part of Nigeria***

***Plans & Estimates Prepared***

**Lagos Address:**

40.A. JOSEPH STREET.

**Ibadan Address:**

GBAGI STREET IDDO GATE.

# OIBO ALAGBON

Ile Owo Ekini ni ile yi ti şi Ile-Qja Titun ti nwọn şẹşẹ kọ si OBDE IDO, IBADAN. Orişirişi Aşọ, Işọ̀şọ Wò-sìwósì, Awo Abọmafọ, Ohun-Elo onirin oniruru ati Ọpọ Orişi Ọja miran lo mbẹ nibẹ

## WA WORAN!!

---

**Ibadan Billiard Saloon**

**Ido Gate, Gbaşi, Ibadan.**

Opposite P. Z. & co..

GAMES:

Billiard, Skittles, Dominoes, Draught, Ludo, Cards and Syrian Draught also Dancing

EXCELLENT MUSIC PROVIDED.

A Bar is attached for the convenience of visitors.

*M. K. Assaf,*
Manager & Commission Agent.

---

MUSTAFA ADENRAN

NI

nişọna Atata ni popo Bode Ọna Ido, IBADAN

Agbada to jire, Ẹwu saro ti gbajumọ, Ẹwu Ọyala ati wọtẹlẹ ati Şokoto ti o şe rẹgi nibẹ lo pin si

**IROHIN KO TO AFOJUBA**

# IṢE OLODUMARE - DISPENSARY

Joshua O. Ade: Craig,
*Manager & Proprietor,*
Re... 1916



BRANCHES AT
AGBENI OSOGBO
& LAGOS.

## KINI TO ALAFIA ?

Egbogi fun orișirişi aisan wọnyi ṣẹṣẹ de si Ile Egbogi ti a npe ni IṢẸ OLODUMARE ni Opopo Gbagi:—

Egbogi, Oyi, Iba, Ikọ, Aiperi, Ọrẹrẹ, Arinka, Lakuregbe, Sobia, Jẹdijẹdi, Akokoro Akandan, Oju, Eti, Ọtutu, Ẹhin, Osi, Egbogi titọju, Aboyun, titọju Ọmọ ọwọ, Aran kinişa, Ẹda, Inọrun, orişirişi Egbogi fun ailera Obinrin.

Egbogi fun ilera Ọmọkunrin, Egbogi fun arun-karun lara Ọmọkunrin ko ma ye ọ. Ya nibẹ ki o mu tirẹ, o le ri Alabojuto laşiri bi o fẹ. Ki Olowo wa, ki Alawin wa, araisan ni ko dara. Iwọ ko tilẹ gbọ orukọ ibẹ ri ndan? "IṢẸ OLODUMARE."

## ANGLO-COLONIAL TRADING CORPORATION, LIMITED.

Broad Street, Lagos, &
OGUNPA, GBAGI STREET, IBADAN
The Cheapest and Best House for
**NEW PROVISIONS**
Wines, Spirits, Beer etc. &
ALSO
Cotton and Sundry Goods

## E. T. SOLOLA,

*General Merchant*
HEAD OFFICE:
39, SERIKI STREET,
P. O. Box, 407,
LAGOS, NIGERIA.

**Dealer in various articles suitable for different kinds of Market in Nigeria.**
**Matchets and Clay Pipes always in stock**
**Enamelwares,**
**Crockery**
**Gunpowder,**
**Hardware,**
**and other articles are obtainable at surprisingly low prices**

**COME ONE, COME ALL**

SHOWROOMS: 3 Martins Street Lagos
Ajaba Square, Ogunpa Road, IBADAN.

Printed and Published by D. A. OBASA at The Ilare Press, Ogunpa Road Ibadan